# ELETI OFE

'A-NJU-WON KO SE WI LEJO'

VOL XIV NO 951 LAGOS SATURDAY DECEMBER 12 — DECEMBER 18 1964 KOBO MEJI ( 2D )


## Ṣi Olubadan Ba Ku Tani Yio Joye ?

# Oba Yesufu Kobiowu Wo Aja

IBADAN – Anu ṣe wa lati gbọ iku Ọba Yesufu Kobiowu OLUBADAN ti ilu Ibadan ni orọ ọjọ Alamisi ti ṣe ọjọ kẹwa oṣu yi, lẹhin igbati o ṣe amodi fẹrẹ.

Ikan ninu awọn ẹbi rẹ fi ye wa pe o to ọjọ mejila nisisiyi ti ologbe na fi ye awọn pe' iba fẹ yọ on lẹnu ṣugbọn lẹhin na o ti ba nwọn lọ ṣe oriṣiriṣi ẹyẹ, papa julọ o lọ ki irun Jimọ ti o kọja yi.

O ni ni iwọn ọjọ mẹrin sẹhin ni amodi na gba ọwọ. Oniṣegun rẹ si ni ko gbọdo kuro ni ori ibusun rẹ. Nigbati a ma wa wo ni agogo mẹta owurọ ijọ *Alamisi, o ti fi aiye yi* silẹ.

Ọba Ologbe na di ọmọ ọdun marun-le-n -adọta ni gbati oku. O ti ẹṣẹ bọ bata baba rẹ Oloye Ogunsiji ti oye rẹ njẹ abẹṣẹ Olubadan

Ni ọdun kọkanlelọgbọn a fi Ologbe yi jẹ Oye Magaji Kobiowu, oye tio ṣe wipe on ni o ṣiwaju fun awọn oye yoku. Ologbe sun lati ori Magaji titi ti o fi jẹ oye Olubadan ni iwọn oṣu mẹfa kọja.

A gbọ wipe Alhaji Salawu Aminu Ba ogun Ilu Ibadan ni oye Olubadan yio kan. A o tẹ oku Ologbe si Mapo ni agogo mẹwa owurọ yi, awọn musulumi ni nwọn yio sin gẹgẹ bi eto ẹsin nwọn.

Ọmọ Ogunsiji, ọmọ a fi irin dara ni orere Oranya, Sun re O. Majẹ ọkun ma jẹ ekolo.

---

# Itan Ore Meta Ti Nwon Ko Le Ya Ara Nwon

Gbogbo bi nkan ti nlọ fun eyi owu aw ko tẹ ni ọrun ṣugbọn ko si ọna miran ti nwọn le gbe ọrọ na gba ju wipe ki nwọn ma wo iṣẹ Oluwa ni ọju.

Nighati suru dagba on na bẹrẹ si da oko pẹlu baba rẹ, Ikore nwọn ni igbana bẹrẹ si d gba si iwaju ju ti akọkọ lọ sibẹsibẹ koi ti tẹ eyi owu awi ni orun gẹgẹ bi o ti nwu.

Ni ọjọ kan o pe iyawo rẹ ati ọmọ rẹ o ni on fẹ wa owo lọ si ilu o ere bo ya nkan yio dara ju bayi lọ fun wa. Iyawo rẹ rọ ọ pe ki o maṣe lọ si idalẹ kan nṣe ni ki o ni suru pẹlu on ti Ọlọrun ba ṣe fun, ki o si fi ara da. Eyi owu awi gbọ ọrọ iyawo ati ọmọ rẹ ko si jade ni ilu ma.

Nigbati o ṣe Ọlọrun tun gbe adanwo mi ka ni aya, gbogbo ọgbin rẹ ko dara iṣu rẹ ko ta, agbado ri o ni erin, ko oro bẹrẹ si ba awọn ewe ẹfọ rẹ jẹ agba ra kaka ni nwọn fi ori eyi ti nwọn lọjẹ ni ile, nkan na wa ruju fun Eyi owu awi d po ti o mọ kini o le ṣe, ṣugbọn ni ikẹhin o ni on yio ma da oko diẹ diẹ on yio si ma ṣẹ igi ta ni igboro, bayi ni Eyi owu aw ṣe di aṣẹgi ta ni ilu ti a bi si.

O nba bayi bọ fun ọdun gbọrọ, ṣugbọn ọmọ rẹ suru ko dẹkun oko rẹ ni dida a si ma bọ iya rẹ ati baba rẹ n nu nkan t o ba mu bọ lati oko, iyawo. Eyi owu awi papa a ma ba ọkọ rẹ lọ si oko igi ni igba gbogbo,

Ni ọjọ kan Eyi owu awi ati iyawo rẹ lọ si oko igi Suru ọmọ nwọn lọ akuro rẹ, ki uwọn to de awọn alejo mẹta kan ti de le fun nwọn, Awọn alejo na jẹ ajoji patapata.

---

## Arikogbon Owe Oyinbo Ni Ede Yoruba

1 Wakati kan ti o fi bi nu, o si rin ẹrin iṣẹju mẹta a e ṣe ti go fi nio igbara rẹ danu.

2. O w ina ọkunrin t fi pupọ ojuu ọjọ aiye nwa obinrin ti o dai Ṣgọ sbẹ sibẹ o ṣe g eya wo gbẹh n ni.

3 Ori buburu ni oguu oṣi.

4 Ẹtọ ni ki kẹtẹkẹtẹ egbe daradara ki o to bọrọ iṣẹ.

5 Bi ti gba asiko ati agbara lati ri ṣe bẹ na ni gba ni ni agbara ati aṣiko lati ma ri ṣe.

6 Ninu ozun igbesi aiye orire loju, ṣugbọn eto ni kọ ni bi a ti ṣe ma gbe ẹsẹ rẹ.

7 Anu ni agbara ti mu n mọ lai sọ iun ni.

8 Bi o ba gbẹkẹle bi o ti to, ko le ran ọ ni ọwọ lai garun ri nkan to wa ninu agbo.

9 Diẹ ninu obinrin 'ni a ko le ba ninu ibaje.

10 Jẹ ki ibajuujẹ rẹ ba orun lọ bi bẹ kọ yio pa ọ ni ẹkun.

# ELETI - OFE

(A NJU WỌN KO ṢE WI LẸJỌ)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAMME

28, Kosoko Street, Lagos, "ELETI-ỌFẸ" Lagos

P. O. Box 467, Phone 23370

VOL. XIV NO 951 SATURDAY Dec. 12 - Dec. 18 1964


## Nwon Tu Ile gbimo Eko Ka

Awọn igbimọ ijọba apapọ ti ilẹ wa ti nwọn ti nṣe ofin le wa ni ori fun ọdun marun ṣẹbin pari iṣẹ nwọn ni ọjọ kẹjọ oṣu yi. Kaluku wọn yio lọ ji yin fun awọn ti o ran nwọn wa nkan ti nwọn fi ọdun marun ṣe. Dajudaju ọdun marun ki ṣe ọmọde ọdun boya ilọsiwaju wa fun wa tabi ko si ninu ọdun marun na.

Laisi aniani gbogbo aiye mọ wipe larin ọdun marun yi ni a gba ominira fun ilẹ wa, ti o si jẹ on pataki kan ti gbogbo awọn orilẹ ede nfẹ julọ. Ninu ọdun marun yi ni orilẹ ede wa wọ ijọ Agbarijọ orilẹ ede (United Nation). Oriṣiriṣi nkan mere-mere miran ni ijọba apapọ na nṣe.

Adupẹ fun gbogbo awọn ti nwọn ṣẹ ijọba 'ti] o koja na fun oye ati ọgbọn pẹlu ifi ara da larin ọdun marun na ti rogbodiyan kankan ko ṣẹle ni arin wọn lasiko ti nwọn ba wa ni ile igbimọ aṣofin.

Ki ṣe wipe ko si asiko kan ninu ọdun marun yi ti iwa ati iṣesi awọn ti o wa ni ori aga ijọba ki ibi awọn alatago ni inu bakanna ni iwa ati iṣesi awọn alatako mbi awọn ijọba ni inu. ṣugbọn adupẹ pupọ fun yin wipe ẹ fi suru ati ifi ara da ba ara yin lo ti odun marun na fi jalẹ. A dupẹ fun yin o.

## Egungun Ko Gbodo Jade Ni Agbe-gbe Remo

SHAGAMU - Gbogbo egungun ko ba ṣe tị ọdun ti gbogbo ilu ni ọwọ si tabi tị idile ti a fi nbọ oriṣa idile ni o tabi egungun a mọmọ jade ko ni sị ni agbegbe Rẹmọ titi ti a o fi dibo pari.

Awọn ẹgbẹ aṣelu UPGA ati NNA ni agbegbe ilu Rẹmọ fi ara mọ ni ipade kan tị nwọn ṣe pẹlu ọga awọn ọ l a p a agbegbe na Ogbeni Yisau Lawani nwọn ni nitoripe ịwa jagidijaga ma sa ba pọ n ị asiko ti nwọn ba nṣe are egungun.

Awọn ti nwọn wa si ịpade na le ni Ọgọrun enia ti wọn wa soju fun ilu nwọn Ọgbẹni Yisau Lawani bẹ gbogbo awọn o ṣ e l u ti nwọn wa ati eyi ti ko wa sị ipade na pe ki onikaluku gbagbe a w ọ n nkan ẹdun ọkọn tị o ti wa nilẹ tẹlẹ tẹlẹ.

O ni on be wọn ki nwọn ma ṣe jẹ ki ọtẹ oṣelu ke okun ifẹ ati ibatan ti o ṣe wịpe ko si iru rẹ n i n u gbogbo ile Nigerịa. Ninu ọrọ rẹ oni ki oṣelu kan ma lo hu asiya oṣelu keji, ki nwọn ma sị kọ orin ebu si ara nwọn. O nị ki nwọn kilo fun awọn ọmọ ogun nwọn ki nwọn ma ṣe ko nkan ọṣẹ wa sị ibi ipade ipolowo ibo.

Ọgbẹni Amoda Lawani ṣe ẹnu f u n ẹgbẹ NNDP. o nị awọn ẹgbẹ UPGA ni wọn ko rogbodiyan wọ ịlu nwọn a ma lu awọn ọmọ ẹgbẹ N N D P ni alubolẹ nwọn a si m a k u n ịlu nwọn ni ina.

Ọgbẹnị Alhaji M, S Sanusi fun awọn ẹgbẹ Alẹnịtẹre fi han ọga ọ l ọ p a wịpe, Atete ki ole, ole nki oloko, o n i iwa jamba po lọwọ awọn NNDP, Nịtoripe awọn nị wọn a ma re asiya UPGA nwọn a si lu nwọn, nwọn tun sare lọ purọ ni ọdọ a w ọ n ọ ọpa ibilẹ, awọn ọlọpa a si ti wọn mo ile.

Nị iparị rẹ Ọga a w ọ n ọlọpa ọgbẹni Yisau Lawa ni pẹlu ọgbẹni T. T, Oketuji sọ wịpe awọn yio pe ipade awọn a d a j ọ ibilẹ Adajọ awọn ọlọpa ati Adajọ k o t u nla ti agbegbe Rẹmọ.

## Gbomo Gbomo W'e won Odun Merinla

UYO — Ni kotu ganran ni ilu Uyo ni Adajọ agba Ọgbẹni M.O Balonwu ti ju ọdaran Edet Archibong eniti a mọ ni onişowo gbọmọ-gbọmọ si ẹwọn ọdun mẹrinla fun ẹṣẹ pe oji ọmọ ọdun mẹwa gbe.

Edet gba ọmọbinrin kan ti ṣe ọmọ ọdun mẹwa ti ore ko rẹ njẹ Ndon Ebom ni ọwọ iya rẹ wipe on yio fẹ ni iyawo on. Edet jẹwọ fun awọn ọlọpa pe ni ododo ni on gba ọmọ na ni ọwọ iyo rẹ wipe on yio fẹ.

O ni on pẹlu ọmọ na jọlọ si ilu Camerounn on si fi si itọju ọrẹ on kan ni ilu Manfe, ṣugbọn nigbati on pada de on ko ri ọrẹ on ati ọmọ obinrin ni ile.

Nidajọ ni on gbọ gbogbo awawi rẹ, ṣugbọn on ko gba ọkan si ododo ninu ọrọ rẹ nitorina ki o lọ ṣe ẹwọn ọdun mẹrinla pere.

## Benson Kuro Ninu Egbe Alakuko

EKO - Oloye T. O, S. Benson ti se oludari eto gbohun gbohun fun ijọba apapọ ti ... jọ Alaruba ọjọ kẹsan oṣu yi igbakeji baba ẹgbẹ Alakuko ti fi iwe ranṣẹ si Baba ẹgbẹ agba ẹgbẹ Alakukọ Dokita Okpara tị ṣe olotu ipinle ila orun wipe on ko ṣe ẹgbẹ nwọn mọ

Nịnu ịwe re si baba ẹgbẹ na, o l o y e Benson nị anu ṣe on lati fi ẹgbẹ na silẹ nitori pe nwọn ko ṣe ẹto pẹlu on nipa yiyan ti nwọn ko yan on lati lọ sujọ ẹgbẹ na ninu ịle igbimọ titun ti a o di ibo fun.

( Wo oju ewe kefa )

# Nwon Gun Omo Ilewe Iobe

IBẸFUN ILADO — Fọlakẹ Adeleye ti nṣe ọmọ ọdun mọkandinlogun jẹ ọmọ ilẹwe Aglican Moden School ni Ibẹfun Ilado ni agbegbe Ijẹbu-Ode ni a gbọ wipe nwọn gun ni ọbẹ pa ni ọsan ọjọ Alamisi ti ṣe ọjọ kẹta oṣu yi.

Gẹgẹbi irohin ti awọn ọlọpa fun wa ni wipe, Fọlakẹ nfi ẹsẹ rin lọ si abule ti a npe ni Odoloka ti o to irin ibusọ meji si Ibẹfun-Ilado.

Awọn ọlọpa fi ye wa we ni agbede meji ọna ni awọn ọkunrin mẹta kan ti yọ si ni inu igbo, nwọn gbe ijo ti ọmọde-binrin yi nwọn si gun ni ọbẹ. nwọn ọlọpa ni awọn nwadi kini o fa rogbodiyan ti o si mu gun ni ọbe wa. Awọn ọkunrin na sa si inu igbo lehin ti nwọn se jamba tan.

A gbọ wipe Fọlakẹ ku nigbati awọn ẹbi rẹ ngbe lọ si ile iwosan ni Ijẹbu Ode. Ni ọjọ Jimọ ti ṣe ọjọ kẹrin oṣu yi, awọn ọlọpa da awọn ọkunrin meji kan duro si ọdọ lati ran awọn ọlọpa ni ọwọ lati wa awọn ọdaran yi.

Oku Fọlake ṣi wa ni ile iwosan ni Ijẹbu-Ode fun ibẹwo oniṣegun ijọba lati mọ nkan ti nwọn fi gun ọmọbinrin na,

## Oiopa Mu Awon Omo Janduku

ONDO — Ija nla kan bẹ larin awọn ẹgbẹ oṣelu meji ni ilu Ondo ni ọjọ Jimọ ti ṣe ọjọ kẹrin ọṣu yi.

Awọn ọlọpa ni ija na bẹrẹ ni ibiti awọn ẹgbẹ kan ngbe ṣe ipade ipolowo ibo awọn kan wa ba nwọn ni ojiji lati da ipade na ru.

Awọn ọlọpa fun wa ni irohin pe Ada, Ọbẹ, Igo ati kumọ ni nwọn bẹrẹ si fi ba ara nwọn ja. Awọn enia mẹta kan ti ọlọpa ko da orukọ nwọn mbẹ ni ile iwosan fun ara ti nwọn fi pa ninu ija na.

Awọn ọlọpa ri ogun ko ninu awon ọmọ oni jagidijagan nwọnyi. Lọwọlọwọ awọn ọlọpa nṣe iwadi.

## Mato Pa Omo Ojeka Kan

AKURẸ — Ọmọde kan ti nkọ iṣẹ mato wiwa ti orukọ rẹ njẹ Kẹhinde ni a gbọ wipe mato tẹ pa larin ilu Akurẹ si Ondo.

Gẹgẹb irohin ti awọn ọlọpa fun wa, Kẹhinde bẹ silẹ lati ẹhin mato nigbati mato na npọn oke kan larin Akurẹ si Ondo ṣugbọn mato na kole pọn oke yi, nigbana ni Kẹhinde ni ki on fi igi tọ ẹsẹ mato na

Aye ti mato yi wa ni ori oke ko gba ki a fi nkanlọ ẹsẹ rẹ nṣe ni o rekọja lori Kẹhinde o si tẹ ẹ pa. Nwọn gbe oku ọmọ na lọ si ile iwosan to wa to ni Akurẹ,

# ElewonDa Kotu Ru

SHAGAMU Darudapọ ba wọn ni kotu ibilẹ ti ilu Shagamu ni ọjọ Satide to kọja. Onidajọ ju Ṣaula Adeyẹmi pẹlu Ọlanipẹkun Adeyẹmi si ẹwọn oṣu mẹrin mẹrin, fun ẹṣẹ wipe awọn yio pa Ọladẹinde nitoripe o nṣe ẹgbẹ Dẹmọ (NNDP).

Nigbati nwọn ro ẹjọ tan ti Adajọ si da nwọn ni ẹbi Ọgbẹni Saula ni on ko jẹbi nigbati Adajọ sọ si ẹwọn oṣu nicun.

(Wo yoku loju ewe karuu

# Kotu Ko Gba Iduro Fun Awon Odaran

IKẸJA — Onidajọ kotu ọlọpa ni Ikẹja Ogbẹni T. A. Makanju kọ lati gba iduro fun awọn ọdaran mẹta. 'Sidi Khayam, Olusẹgun Adebayọ ati James Abam.

Awọn mẹta nwọnyi pẹlu ọmọ ilu Oyinbo kan ti a npe ni Dokita Allen ni a da ni ẹbi ni oṣu ti o koja pe nwọn jẹbi iditẹ lati si oju ijọba apapọ delẹ. Onidajọ ni ki ẹnikọkan nwọn lọ ṣe ẹwọn ọdun kan

Awọn ọmọ ilẹ wa mẹta ti a da oruko nwọn si o e sọ wipe awọn ko jẹbi nitorina awọn fẹ ki ẹjọ na lọ si iwaju awọn onidajọ agba, pe ejọ kotẹmilọrun.

Nigbati agbẹjọro nwọn bere iduro fun nwọn ni ọjọ Satide ti ṣe ọjọ karun oṣu yi ni iwaju onidajọ awọn ọlọpa: Onidajọ na kọ jalẹ lati gba iduro fun wọn.

Adajọ ni otitọ ẹsun iṣ iwa hu ni eṣe ti nwọn sẹ, oni ṣugbọn gbogbo aiye ni o ti ri iwa ti Dokitọ Allen hu lasiko gan ti a gba iduro fun. O gbiyanju lati gbe iduro na fo koja ki o si salọ ṣugbọn ọwọ tẹni idi iroko.

Adajọ ni nitorina eyi ti a ti ri ni apẹrẹ siwaju ti ọgbọn fun ni lati gba wipe awọn nwọnyi na le ṣe bẹ. Nitorina nko ni uka kan miran ni apẹrẹ ti o le mu mi gba idero fun awọn ọdaran yi.

# Musulumi Ko Gbodo Ni Iyawo Marun

KAFANCHAN - Nọsẹ ti o kọja ni a mu Usuman ọba awọn Fulani ti o wa ni Kagoro ileto kan lẹba ilu Kafanchan wa si iwaju kotu Alikali ti nbẹ ni ilu Kafanchan fun ẹsun pe o ni iyawo marun.

Nigbati Alkali bere lọwọ rẹ pe eṣe ti o fi ni iyawo marun? Usuman ni ki adajọ fi ori ji on, O ni awọn obi on ko bi ọmọ pupọ, on si fẹ lati ṣe aoiyamọ pupọ ni o mu ki on fẹ iyawo karun.

Alikali ri Usuman jẹbi itapa si apakan ninu ofin ẹsin musulumi o ni Musulumi kan ko gbọdọ ni ju iyawo mẹrin lọ. Nitorina ki o san Ọgọrun pọun tabi ki o lọ si ẹwọn oṣu mọkanla.

Alikali ni ki mallam bafada Baladace ti ṣe baba iyawo usuman karun lọ san pọun mẹdogun tabi ẹwọn oṣu meji nitoripe o fi ọmọ rẹ fun ẹniti iyawo rẹ ti pe mẹrin,

Alikali na pa laṣẹ fun Baba iyawo na pe ki o lọ da owo ifẹ ti Usuman san le ọmọ rẹ lori pada fun kiya kiya. o ni on si ja yigi ti nwọn so larin Usuman ati Azumi ti ṣe iyawo karun.

# Jamba Mato

KADUNA – **Agbo** wipe ọgbẹni Osita Awani tị şe agba ero mato tị o sị **ba** mato rẹ kuro ni ilu Eko lati wa si ilu **Kaduna lẹhịn igba** ti a tị ko awọn ilẹkun irin si inu malo **rẹ.**

Irohịn kan wa pe **nigbati mato** rẹ de agbede meji ịlu Minna sị ilu **Kaduna si ikan ninu** taya mato na bẹ ni ojịj, o da nwọn **nu, Osita awani** ku sịbẹ ni ẹsẹ kanna. Eniti nwa mato ọgbẹnị **Peter** okoye fi ẹsẹ ro, o wa ni ile iwosan Kadnua.

Nị ibusọ kẹsan larịn ilu Kaduna si ilu Zaria ni a gbọ wipe isẹlẹ mato miran tun şẹ̣ l rin awọn B. s meji.

Bosi **kan** tị nii Zaria bọ pẹlu eyị ti ntị **Kaduna** bọ fi ori gba ara nwọn, enia mẹta ninu awọn ero ịnu nwọn ni wọn ti ara pa.

A ti gba awọn ero t awọn fi ara pa na si ileiwo-san nị ịlu Kaduna.

# Ilewe Ologun Fun Awon Omo Binrin

ZARIA - Ọlọla Alhaji Muhammadu Rịbadu tị şe oludari eto işẹ ologun ijọba apapọ sọ nị ilu Zaria nigbati awọn ologun marundịnlogoji pari ẹkọ nwọn ti o sị fun ni iwe ẹrị pe

Ni a i pẹ yị a kọ kun ile ikọşẹ ologun nitori ki a le kọ awọn ọmọ wa obin na ni işẹ ogun. O tị işẹ ogun ti ajịye ti a wa yi jẹ i kan ti o ruju ti o sị nfẹ iye ati imọ.

O ni nwọn yịo ri awọn ọgagun die mu jade ninu nwọn laipẹ yi. O ni ki awọn ọmọ ịle ẹkọ na fi oju si ẹkọ nwọn ki nwọn si şe işẹ pẹlu ẹ̣uun ọkọn nwọn.

O ni on fẹ ki nwọn fun awọn ọmọ ile ẹko ologun ni ẹkọ ti o ga, ti yio jẹ ẹko mo mọ şe ti ki şe mo n.o ka rịkae. Nitori ki o le fi ipasẹ nwọ le ọna olotu tabi aşịwaju ni ọba.

Ni pa bayi nwọn yịo fun yin ni ẹkọ ịjinlẹ tị ẹ o si ma gba iwe ẹri ẹkọ gi ga ti ẹ o fi ni ma wọ lewe ọjọgbọn ti ile wa ajhin tabi ni ilu okere.

# Itan Igbehin Oga Buruku

Ọkunrin Olowo kan wa ni igba kan, o si buru pupọ. Ni gbogbo ịgba ni o ma tu awọn mẹkunnu jẹ ni ọjọ kan ọkunrin yi gba omọde kan si ịşẹ o sị ni on yio ma fun ni pọun mejị ni oşu, şugbọn pẹlu adehun kan ni, o nị ki on to san owo fun tị oşu ba pari, ọmọde yi yio wa ikan mejị wa fun on. Ọmọ na gba bẹ nigbati ko ri işẹ miran.

Ọmọ yi bẹrẹ işẹ o si şe ịşẹ rẹ daradara ti oşu fi pari. Nigbati oşu pari o tọ ọga rẹ lọ lati bere owo işẹ rẹ şugbọn ọ sa na ja igbe mọ o ni a fi ki o lọ wa TAKỌ TABO wa fun on kị on to san owo rẹ. Ava ọmọde na la wa bi igb ti ara ko ba san, o si bị ara rẹ lere pe kinị akọ kini Abo ti ọkunrin yi nfẹ ki on mu wa. şugbọn omọde yi papa nị ọgbọn Arekende tirẹ.

O wọ ịnu igbo lọ o ri alantakun nla kan o mu o de mọ ịnu igo kan o si tun wa akeke kan ri o de mọ inu ịgo kan, o gbe wa fun ọga rẹ.

Nigba i o gbe de ọga rẹ nị ewo ni o wa inu igo nwọnyi? Ọmọ gbe igo akeke fun ọ ni Ako ni yi, o ni ki ọga on fi ọwọ rẹ si igo ki o wo, bi ọga ti fi ọwọ si ịnu igo ni akeke ta ni ọwọ. O kigbe

Ọmọ nị kị o fi ọwọ si igo keji ko wo Aboọ ọga ni o ti, gba pọun mẹji rẹ ki o ma lọ.

# Egbe Oselu Yin Ibon Si Arawon

OLEH Ọgbẹni Titus Chukwuma ti şe aşọde oru pẹlu ọkọn ninu awọn oşelu fi ara gba ọgbẹ nigbati ịja bẹ sẹ larin awọn ẹgbẹ M D F lati ẹgbẹ UPGA ni ịha Mid-West ri ọsẹ to kọja.

Gẹgẹ bi irohin ti awọn Ọlọpa fun wa, nwọn ni rogbodiyan yi bẹrẹ nigbati awọn ẹgbẹ Alakukọ ndari bọ ibi ti nwọn ti lọ pe Olowo ibo lẹhin igbati nwọn ti lọ kakiri agbegbe Isoko tinwọn nwọn si npada bọ niOleh.

Nwọn ni awọn kan ta ibọn si mato nwọn Ọgbẹni Chukwuma ti o duro lati wo iran nigbati o nlọ si ibi işẹ rẹ fi ara gba ọgbẹ.

A gbọ wipe moto meji ni nwọn sun ni ina, enia pupọ si fi ara pa ninu awọn ọmọ ẹgbẹ Oşelu.

# Obinrin Kan Ro-jo Orun

IBADAN - Obinrin ọmọ ọdun merinlelogun ti a npe ni Asiawu Aṣeṣo ni fun Adajọ kotu ibilẹ ni Ibadan pe on kuro ni ile ọkọ on ti a npe ni Tiamiyu Adigun nitoripe "KO PE ON NI ORUN NI".

Ọkọ ọmọ obinrin yi Tiamiyu jẹ alapata ni adugbo Lekuro ni ilu Ibadan On ni o pe iyawo rẹ Aṣawu ni ẹjọ si kotu ibilẹ pe on fẹ gba pọun mẹwa ni owo iyawo na nitoripe o kọ on silẹ.

Nigbati kotu bi Aṣawu lere pe kini ọrọ tirẹ ni jẹ. Aṣiawu ni s wiju na ko si itẹju, o yi oju si ọkọ rẹ o bere bayi pe "Bi o ko ba ni agbara lati bo mi, o tun ni agbara lati pe mi ni orun ni ?

Ọgbẹni Tiamiyu ko ri esi kankan fun iyawo ni ori ibere pataki yi, ju wipe on sa gbogbo agbara on lati fi tẹ Asiawu l'orun.

Ninu idajọ rẹ, Onidajọ na sọ fun Ọgbẹni Tiamiyu pe ki o fi Aṣiawu silẹ ki o lọ lati ko bere kọbọ ni ọwọ rẹ tabi ki o wa ọna ti ifẹ yio fi pada si arin nwọn

Adajọ ni Tiamiyu lọ san pọun meji şile meji fun Asiawu owo irin ẹsẹ.

---

# Elewon Da Kotu Ru

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

O fa ada ti awọn abọgun ufi bura ni kotu yọ. o ni on yio pa Onidajọ.

Saula le gbogbo ero kotu ati awọn Ọlọpa ibilẹ jade kuro ni kotu on papa ki are mọlẹ o si salo mọ nwọn loju. Awọn Ọlọpa nwa Saula Adeyẹmi lọwọlọwọ yi.


# NATIONAL BANK OF NIGERIA LIMITED



**Incorporated in Nigeria in 1933**

**Paid up Capital – £3,181,000**

## HEAD OFFICE :

82/86, Broad Street, Lagos, Nigeria
Telephone 20511
Cables & Telegrams NATIONBANK LAGOS.

## LONDON OFFICE :

15, THROGMORTON AVENUE, E.C 2.
Telephone LONDONWALL 4303.
Cables & Telegrams NATBANIGER LONDON

## 30 BRANCHES IN NIGERIA

CORRESPONDENTS IN ALL PARTS OF THE WORLD
EVERY DESCRIPTION OF BANKING BUSINESS TRANSACTED.

# Itan Igbesi Aiye Anobi Mohammed

By Alhaji T. K. Oshish

بسم الله الرحمن الرحيم

Nịgbati Haleemọh gbe Anobị de ile, bẹnị ewurẹ rẹ ti o tị ru kangẹrẹ fun aiko maye oṣu sanra de nị o fi ọwọ tị o fi gbe Anobi pa nị ara. gbogbo ekuru ara rẹ gbọn danu.

Bakanna nị Rakunmi nwọn ti o tị wo lulẹ l'ọjọ tị o jina, ị dịde o si di eni i nfun ọmọ rẹ ni omu, ba yị ni Haleemot ṣe di ọlọrọ enia, on ati ọkọ rẹ Awọn ara ilu a ma pe obinrin na ni Haleemot Shaadya nitoripe Shaady ni ịlu rẹ. Haleemot tọọ Anọbi fun ọdun mẹrin kị o to gbe pada fun iya rẹ Aminot.

A yọ Inuribini; ẹgan kẹnị ma nị, ịrira ọmọ lakeji, Ibinu, ọkanjuwa, tembẹlekun ati oniruruiwa ti ko ba oju mu kuro ni ọkan Anobi lati kekere. Ba yi Alukoran ṣe sọ wipe Awa ṣe afọmọ ọkan rẹ, awa si sipaya ịgbaya rẹ fun ọ.

Ni ọjọ kan Anọbi pẹlu ọmọ Haleemot jade lọ ṣe are ni ẹhin ịle nwọn ni nwọn Mọlaịkat meji kan de nwọn gbe Anọbị mora, nwọn sị ṣe afọmọ ọkan rẹ. Nigbati nwọn de ile ọmọ Haleemot sọ fun baba ati iya rẹ ịru ọkan abamị ti ṣẹlẹ Anobi.

Awọn amọye ninu awọn iran Jew ati Chrịstian tị nwọn ri aperẹ pe ẹnị aba tai nị Muhammed ti wa ọrọ rẹ nị ọwọ Haleemot atị ọkọ rẹ ko gba. Ẹru bẹrẹ si ba awọn mejeji nị tori ki awọ ịjẹ Jew atị christian ma gbe ọmọ na lọ pa.



Alhaji T K Ọshishi

# Benson Kuro Ninu Ẹgbẹ Alakuko

Oloye Benson ni on ti koja eniti uwọn yio ma sọ fun wipe ki o kọ iwe iyan ni tu ibo wa, o ni gẹgẹ bi ipo on ẹtọ ni ki nwọn wa aye fun on tabi ki nwọn fi on silẹ nibiti on ti dịbo wọ ile ni e meji.

Oloye Benson ni ifi ara mọ irankan ju ikan lọ pọ ninu ẹgbẹ awọn, O ni gbogbo enia kọ ni ofin na ni paṣan, o ni nkan ti ẹgbẹ sọ ni pe awọn alaṣaro adugbo ni nwọn nị lati yan ẹnitị a o di ibo fun, o nị nwọn ko ṣa bẹ ni Ilesha, Ibadan, Benin, Nsuka ati awọn ilu omiran.

Oloye Benson ni ịlẹgun ko yị ti ti fun ịpari ija yi, bị bẹkọ on yio gbe apoti ịbo ti on sị ịta.

# Awe Yio Bere Ni osu Januari

IBADAN — Awọn igbimọ tị o ga ti o si kun fun awọn Imamu ati awọn Alufa nla nla nị ipinlẹ Iwọ Orun ṣe ipade latị fi ọjọ ti ao bẹrẹ awẹ tị nbọ yị mulẹ.

Ninu abayọri ipade na nwọn pinu pe awẹ yio bẹrẹ ni ọjọ kẹrin oṣu Januari ti ọdun tị mbọ. Eyi jẹ ipinu kan pataki tị awọn akojọ Musulumi ṣe fun ilọsiwaju ẹsịn nwọn.

Nwọn ni gbogbo Musulumi ipinlẹ Iwọ Orun gbọdọ gba awẹ ti oṣu kini, ọdun tị nbọ ba mẹrin nwọn ri oṣu nwọn ko ri oṣu o, awọn fi si ipinu wipe ki nwọn bẹrẹ awẹ.

Alaga eto ilọsiwaju ẹkọ Ọgbeni Alhaji Issa Sumọnu Mọgaji sọ fun ipade na pe o tọ ki gbogbo ilewe Musulumi ipịnlẹ wa ni eto kan na fun ẹkọ nipa ede awọn Larubawa.

O orị gbogbo Imamu tị ilu Ibadan Alhaji Muilị bẹ gbogbo awọn ti wọn wa ni ipade na pe ki gbogbo Musulumi ṣiwọ kuro nibi a ngba owo ibọlẹ tabi a nṣe eru. O ni ki nwọn tẹle ẹkọ ti ẹsin Musulumi kọ nwọn, ki a le gbe ẹsin wa nịyị gẹgẹ bi ẹsin na ti rị.

Ọpọlọpọ ijọ Musulumi ni nwọn ti Ijẹbu Ode, Abẹokuta, Ọyọ, ati ni origun mẹrin ipinlẹ Iwọ-Oruu wa.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street, Lagos Phone 23370.
OLOTI B. A. CAREW 43. Offin Road, Lagos